NYC Housing Connect

Àwọn Àkójọ Àyẹ̀wò & Ohun Àmúlò

Lẹ́yìn tí o bèrè fún Ilé Àìwọ́n:

# Àwọn Àkójọ Àyẹ̀wò àti Ohun Àmúlò



NÍPA ÌTỌ́NI YÌÍ

Àwọn ìbéèrè fún ilé àìwọ́n ni a ń yàn fún àtúnyẹ̀wò nípasẹ̀ ìlànà tẹ́tẹ́ oríire. Tí nọ́mbà rẹ bá jẹyọ nínú tẹ́tẹ́ oríire náà tí ìbèrè rẹ sì farahàn bí èyí tó kún ojú òṣùwọn, a ó fìwépè ọ́ láti ṣètò ìpàdé láti ṣàrídájú àmúyẹ rẹ. Ìpàdé náà ni wà láti ṣàtúnyẹ̀wò àwọn ìwé tó faramọ́ àlàyé lórí ìbèrè rẹ.

Àwọn ètò ìpàdé ni a máa ń ṣe láti oṣù méjì sí mẹ́wàá lẹ́yìn ọjọ́ tí ìbèrè náà ti dópin. A ó bèrè lọ́wọ́ rẹ láti mú àwọn ìwé nípa àwọn tí yóò máa gbé pẹ̀lú rẹ wá, iye owó àpawọlé ẹnìkọ̀ọ̀kan tí yóò máa gbé pẹ̀lú rẹ, ibùgbé tí o wà lọ́wọ́lọ́wọ́, àti àlàyé míràn.

Ìtọ́ni yìí ń ràn ọ́ lọ́wọ́ láti gbáradì fún ìpàdé náà, tí nọ́mbà rẹ bá jẹyọ ní àìrò tẹ́lẹ̀. Ó ń ṣàkójọ àwọn ìwé tí o le ní láti mú dání ó sì ń fún ọ ní lórí bí o ti le rí kí o sì pèsè àwọn ẹ̀dà tí o nílò.

# Mọ̀lẹ́bí Àwọn Ìwé Àkọsílẹ̀

Tí a bá kàn sí ọ fún ìpàdé kan láti ṣàrídáju àmúyẹ rẹ, a ó sọ fún ọ láti mú ÀWỌN ẸDÀ ti àwọn ìwé àkọsílẹ̀ rẹ wá èyítí ń jẹ́rìísí àwọn ènìyàn nínú mọ́lẹ̀bí rẹ. Jọ̀wọ́ máṣe mú àwọn ojúlówó ìwé wá, àyàfi tí abá bèrè. Àwọn ẹ̀dà ti àwọn ìwé wọ̀nyí yóò wà nínú fáìlì – o kò ní gbà wọ́n padà.

Olùkọ́lé náà yóò jẹ́ kí o mọ irú àwọn àkọsílẹ̀ tí o ní láti mú wá. Gbogbo àwọn ìwé ìsàlẹ̀ yìí ni a le bèrè.

ṢÉ ÑJẸ́ O NÍ ÀWỌN ÌWÉ WỌ̀NYÍ BÍ?

## Ibùgbé Tí o Wà Lọ́wọ́lọ́wọ́

- ☐ Ẹ̀dà ìwé àdéhùn ilé yíyá rẹ ìsinsìnyí, tí o bá yá ibùgbé tìrẹ. Tí o kò bá ní ìwé àdéhùn ilé yíyá, lẹ́tà àrídájú tí a fọwọ́sí lábẹ́ òfin láti ọ̀dọ̀ onílé rẹ.
- ☐ Ẹ̀dà ìwé ẹ̀rí owó-sísan fún ìyálégbé ilé yíyá tí oṣù mẹ́ta (3) sí oṣù méjìlá (12) tàbí àwọn àyẹ̀wò ilé yíyá tí a fagilé.
- ☐ Ẹ̀dà ìwé owó iná tàbí ti gáàsì àìpẹ́ (ní orúkọ rẹ tó sì ń ṣàfihàn àdírẹ́ẹ̀si ìsinsìnyí).
- ☐ Ẹ̀dà ìwé owó ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àìpẹ́ rẹ (ní orúkọ rẹ tó sì ń ṣàfihàn àdírẹ́ẹ̀si ìsinsìnyí).
- ☐ Tí o kò bá yá ibùgbé ti ara rẹ tí o sì ń gbé pẹ̀lú ẹlòmíràn, mú lẹ́tà àrídájú wá láti ọ̀dọ̀ ẹnití ẹ jọ ń gbé pẹ̀lú ẹ̀dà ìwé àdéhùn ilé yíyá àti ẹ̀dà ìwé owó ohun àmúlò.

**Níbo ni mo ti le ṣe àrídájú àwọn ìwé lábẹ́ òfin?**

- Àwọn aṣojú ìṣàkóso ohun ìní àti àwọn ilé-iṣẹ́ owó-orí abẹ́lé tàbí òfin máa ń ní awọn tí ń ṣe àrídájú ìwé lábẹ́ òfin lára àwọn òṣìṣẹ́ wọn lọ́dọ̀.
- Ọ̀pọ̀ àwọn ilé-ìfowópamọ́ yóò le ṣe àrídájú àwọn ìwé lábẹ́ òfin àti pé iye owó.

## Àwọn Mọ̀lẹ́bí

- ☐ Ẹ̀dà ìwé-ẹ̀rí ọjọ́-ìbí fún ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú mọ̀lẹ́bí
- ☐ Ẹ̀dà àwọn káàdì Ààbò Ìgbàlódé fún ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú mọ̀lẹ́bí náà
- ☐ Ẹ̀dà ID àwòrán fún gbogbo ènìyàn tó ju ọdún 18 lọ (àpẹrẹ: ìwé àṣẹ ọkọ̀ wíwá, ìwé ìrìnà, ID Ológun, ID Ìjọba Abẹ́lé NYC, ID àìṣe awakọ̀)
- ☐ Ẹ̀dà àwọn lẹ́tà ilé-ìwé tí ń jẹ́rìísí àyíká fún ẹnìkọ̀ọ̀kan tí ń lọ ilé-ìwé (àwọn àpẹrẹ: Ilé ìwé ìjọba ti New York City, ilé ìwé àdáni, ilé ìwé gíga, ilé ìwé yunifásítì)

## Báwo ni mo ti le bèrè àwọn ìwé ìdánimọ̀?

ÌWÉ ẸRÍ ỌJỌ́- ÌBÍ
Àkókò tí a ó fi Ṣiṣẹ́ lée Lórí Ìlànà Iṣẹ́: Ọjọ́ 2 sí Ọ̀sẹ̀ 8 | Iye owó: ~$15–$25

- Àwọn Ìbí New York City: Ẹ̀dà ìwé ẹ̀rí ọjọ́- ìbí ti ìjọba New York City ni a le bèrè lórí ẹ̀rọ ayélujára, lójúkojú, tàbí nípasẹ̀ í-méèlì nípasẹ̀ Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ìlera àti Ìmọ́tótó ti Ọpọlọ ti Ilẹ̀ NYC. Ó jẹ́ $15, pẹ̀lú iye owó ìfíwéránṣẹ́ $9 àti ìdíyelé iṣẹ́. Àwọn ìbéèrè orí ayélujára ni a ń ṣiṣẹ́ lé lórí láàrín wákàtí 24. Ṣàbẹ̀wò sí http://www.nyc.gov/doh tàbí pe 311 fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé.

- Àwọn ìbí níbòmíràn ní United States: Àwọn ìwé ẹ̀rí ni a le bèrè lọ́wọ́ ọ̀ṣìṣẹ́ agbègbè tàbí ti ilé-iṣẹ́ ìpínlẹ̀ ti àwọn àkọsílẹ̀ tó ṣe pàtàkì. Láti wá ilé-iṣẹ́ àwọn àkọsílẹ̀ ìpínlẹ̀ to ṣe pàtàkì, jọ̀wọ́ ṣàbẹ̀wò sí http://www.cdc.gov/nchs/w2w.htm tàbí bèrè ìrànwọ́ ní ilé-ìkàwé àdúgbò rẹ.

KÁÀDÌ ÀÀBÒ ÌGBÀLÓDÉ
Àkókò tí a ó fi Ṣiṣẹ́ lée Lórí Ìlànà Iṣẹ́: Ọ̀sẹ̀ 2 sí 6 | Iye owó: Ọ̀fẹ́

- Mú kan ní ilé-iṣẹ́ Ààbò Ìgbàlódé àdúgbò rẹ àti/tàbí Káàdì Gbọ̀ngán. Láti rí ilé-iṣẹ́ àdúgbò rẹ, pe 1-800-772-1213 tàbí lọ sí http://www.ssa.gov/cardcenters/cardcenterinfo.html.

ID ONÍ FỌ́TÒ TÀBÍ ÌWÉ ÀṢẸ ÌWAKỌ̀ TI ÌLÚ NEW YORK
Àkókò tí a ó fi Ṣiṣẹ́ lée Lórí: Ọ̀sẹ̀ 2 sí 4 | Iye owó: $10–$80

- Kọ̀wé sí Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ọkọ̀ ti Ìpínlẹ̀ NY fún ìwé àṣẹ ìwakọ̀ tàbí ID oní fọ́tò tí àìwakọ̀. Ṣàbẹ̀wò sí Visit www.dmv.ny.gov/license.html fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé, wá ẹ̀ka àdúgbò rẹ ní http://www.dmv.ny.gov/offices.htm, tàbí pe 1-212-645-5550 tàbí 1-718-966-6155 fún àlàyé.

IDNYC: NEW YORK CITY MUNICIPAL ID

- IDNYC jẹ́ káàdì ìdánimọ̀ ọ̀fẹ́ fún gbogbo olùgbé New York City. Ṣàbẹ̀wò sí www.nyc.gov/idnyc láti bẹ̀rẹ̀ bèrè rẹ lórí ayélujára, tàbí pe 311.

## Níbo ni mo ti le ṣe ẹ̀dà àwọn ìwé?

- Ilé-ìkàwé Ìjọba Brooklyn Pe 311 tàbí lọ sí www.brooklynpubliclibrary.org
- Ilé-ìkàwé Ìjọba New York Pe 311 tàbí lọ sí www.nypl.org fún Bronx, Manhattan, àti àwọn ẹ̀ka Staten Island
- Ilé-ìkàwé Ìjọba Queens Pel 311 tàbí lọ sí www.queenslibrary.org
- Ilé-iṣẹ́ ìjọba ti àdúgbò rẹ Pe 311
- Àwọn Ìsọ̀ ìtẹ̀wé àti ẹ̀dà ìwé

# Àwọn Ìwé Owó Àpawọlé

Owó àpawọlé ní ọdún ti mọ̀lẹ́bí rẹ jẹ́ “àpapọ̀ owó” tí gbogbo ẹni tó ju ọdún 18 lọ gbà tí ń gbé pẹ̀lú rẹ. “Owó àpapọ̀” túmọ̀ sí ohun tí agbanisíṣẹ́ rẹ san fún ọ ṣájú owó-orí. Owó àpapọ̀ rẹ máa ń sábà ju owó àmúrelé rẹ lọ. (Àkíyèsí: Tí o bá jẹ́ oníṣẹ́-àdáni, wàá jábọ̀ owó àmúrelé rẹ lẹ́yìn àwọn àyọkúrò.)

Gba ọ̀pọ̀ gbogbo ìwé àkọsílẹ̀ tí o le gbà. IRS wípé àwọn ìwé ìsàlẹ̀ wọ̀nyí jẹ́ ẹ̀rí owó àpawọlé tí a le gbà. Pèsè ìwé owó àpawọlé fún gbogbo mọ̀lẹ́bí tó ju ọdún 18 lọ.

ÑJẸ́ O NÍ ÀWỌN ÌWÉ WỌ̀NYÍ BÍ?

**Kíni ìdí tí àwọn ìwé wọ̀nyí fi ṣe pataki?**

HPD àti HDC nílò gbogbo àwọn ìwé wọ̀nyí láti jẹ́rìísí kí wọ́n sì ṣírò àpapọ̀ owó ọdún tí mọ̀lẹ́bí rẹ ń pa – láti iṣẹ́ òjọ́ àti àwọn orísun míràn.

## Owó Àpawọlé Iṣẹ́ Mọ̀lẹ́bí

Ǹjẹ́ ẹnikankan nínú mọ̀lẹ́bí rẹ ń gba owó oṣù tàbí owó wákàtí bí? Olùkọ́lé náà yóò sọ fún ọ irú àwọn ìwé tí o nílò. A ó bèrè àwọn nkan wọ̀nyí lọ́wọ́ rẹ, fún mọ̀lẹ́bí kọ̀ọ̀kan:

- ☐ Ẹ̀dà mẹ́fà (6) ti ìpamọ́ ìwé ìsanwó àìpẹ́
- ☐ Ẹ̀dà àwọn fọ́ọ̀mù W-2 ti ọdún tó kọjá (gbogb ojú-ìwé)
- ☐ Ẹ̀dà àwọn ìdápadà owó-orí tí ìjọba ìpínlẹ̀ àti àpapọ̀ eyítí o kún tí a sì buwọ́lù láti ọdún tó kọjá
- ☐ Ẹ̀rí ìsanwó (àwọn lẹ́tà àrídájú lábẹ́ òfin láti ọ̀dọ̀ agbanisiṣẹ́)
- ☐ Àwọn ìwé àtẹ̀jáde ti ilé-ìfowópamọ́ tó faramọ́ owó tí o san

Ǹjẹ́ ẹnikẹ́ni nínú mọ̀lẹ́bí rẹ ní iṣẹ́ àdáni bí? Fún mọ̀lẹ́bí kọ̀ọ̀kan tó ní iṣẹ́ àdáni, pèsè àwọn ẹ̀dà ti:

- ☐ Ẹ̀dà Fọ́ọ̀mù 1040 tí a buwọ́lù ti ọdún 3 sẹ́yìn, pẹ̀lú ètò C, E tàbí F
- ☐ Ẹ̀dà ti gbogbo 1099 láti ọdún 3 sẹ́yìn
- ☐ Ẹ̀dà ọdún 3 ti ìdápadà owó-orí ti ìpínlẹ̀

## Owó Àpawọlé Mọ̀lẹ́bí láti Àwọn Orísun Míràn

O gbọ́dọ̀ ṣàfihàn àwọn ìwé nípa gbogbo owó tí o gbà, kódà tí kò bá jẹ́ láti iṣẹ́ tí o ṣe. Olùkọ́lé náà yóò sọ fún ọ irú àwọn ìwé tí o nílò. A ó bèrè àwọn nkan wọ̀nyí lọ́wọ́ rẹ, fún mọ̀lẹ́bí kọ̀ọ̀kan:

Ǹjẹ́ ìwọ o ń ànfàní tàbí ò ń gba owó àpawọlé tí a ṣàkójọ nísàlẹ̀ wọ̀nyí? Ẹ̀dà ti ìwé àkọsílẹ̀ fún:

- ☐ (Àwọn) lẹ́tà àmì ẹ̀yẹ Ààbò Igbàlódé fún ọdún kàlẹ́ndà tó kọjá láìpẹ́ (èyítí ó kéré sí ọjọ́ 30)
- ☐ Àwọn Ànfàní Arúgbó (ìwé àkọsílẹ̀ ọdọdún)
- ☐ Owó àpawọlé láti àwọn ohun ìní tí a yá síta
- ☐ Lẹ́tà Ètò Ìṣúná Ìrànlọ́wọ́ Ìjọbà
- ☐ Àwọn Àfipamọ́ Jagunjagun

Ǹjẹ́ ìwọ ń gba owó àjẹmọ́nú àti/tàbí owó ọdọdún bí?

- ☐ Ẹ̀dà ìwé àkọsílẹ̀ láti (àwọn) ilé-iṣẹ́ aláṣẹ

Ǹjẹ́ ìwọ gba ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ àti/tàbí owó ọ̀fẹ́ bí?

- ☐ Ẹ̀dà àwọn lẹ́tà àmì ẹ̀yẹ

Ǹjẹ́ ìwọ ń gba owó ìkọsílẹ̀ àti/tàbí àtìlẹ́yìn ọmọ bí? Pèsè ẹ̀dà:

- ☐ Ẹ̀dà ìpínyà tàbí (àwọn) àdéhùn ìparí ìjà tí ń sọ iye owó àti irú àtìlẹ́yìn àti ètò ìsanwó
- ☐ Ẹ̀dà ìwé àkọsílẹ̀ ti ìjọba tàbí àtẹ̀jáde (tó wà láàrín ọjọ́ 120 tó gbẹ̀yìn tó sì ń ṣàfihàn iṣẹ́ àti iye owó), tàbí ìwé àrídájú lábẹ́ òfin tí a kọ.

Ìdójútòfò abarapá, ìsanwó òṣìṣẹ́, àti/tàbí owó ìdópin iṣẹ́?

- ☐ Ẹ̀dà mẹ́fà (6) ti ìpamọ́ ìwé ìsanwó tabí lẹ́tà ìjẹ́rìísí

Ǹjẹ́ ìwọ ń gba àjọ ìgbàdégbà àti/tàbí ẹ̀bùn bí? Ǹjẹ́ ìwọ ń gba ọ̀nà owó ìgbàdégbà míràn bí?

- ☐ Àkọsílẹ̀ àrídájú àti/tàbí ọ̀rọ̀ àkọsílẹ̀ tí a buwọ́lù nípasẹ̀ ẹni tí ń pèsè ìrànlọ́wọ́ náà, pẹ̀lú èrèdí owó náà, àwọn déètì àti iye (àwọn) ẹ̀bùn náà, àti irú ìgbà tí a ń pèsè ẹ̀bùn náà (ọ̀sọ̀sẹ̀, oṣoṣù, ọdọdún).
- ☐ Àwọn àkọsílẹ̀ ilé-ìfowópamọ́ tó faramọ́ gbígbá àwọn owó yìí

# Àwọn Ìṣòro Àmúyẹ

O gbọ́dọ̀ kọ èyíkéyìí ìṣòro tí o ti dojúkọ sílẹ̀ pẹ̀lú àwọn onílé rẹ tó kọjá tàbí pẹ̀lú gbèsè rẹ. Kódà pẹ̀lú àwọn ìwé wọ̀nyí, kò sí ìdánilójú pé wàá yẹ fún ibùgbé kan. A sì le kọ ìbèrè rẹ, kódà pẹ̀lú àwọn ìwé tó dára.

## Àwọn Ìṣòro Onílé Tókọjá

Ǹjẹ́ onílé kankan tí pè ọ́ lẹ́jọ́ tẹ́lẹ̀ fún ìdí kankan bí? Tó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ni, mú ẹ̀dà wá:

- ☐ Gbogbo ìtọ́kasí òfin
- ☐ Èyíkéyìí ìdájọ́ òfin tó parí
- ☐ Àwọn ìtẹ́lọ́rùn pẹ̀lú ilé-ẹjọ́

## Àwọn Ìṣòro Gbèsè Tókọjá

Báwo ni ìtàn gbèsè rẹ?

Tí a bá yànọ́ fún ìpàdé kan láti ṣàrídájú àmúyẹ, gbèsè rẹ le ṣokùnfà àbájáde ìlànà ìpinnu náà. A kò le sọ wípé o ko yẹ nítorí iye gbèsè rẹ nìkan, ṣùgbọ́n àlàyé inú ìtàn gbèsè rẹ ṣe pàtàkì. Tí o bá ní èyíkéyìí ìwé àkọsílẹ̀ nípa gbèsè rẹ, o le fẹ́ láti gbàà ṣáájú. Fún àpẹẹrẹ:

- ☐ Lẹ́tà tó ṣàfihàn ìlàjà ti àwọn ìṣòro gbèsè tàbí àwìn
- ☐ Ìtẹ́lọ́rùn ti liẹni tí a sanwó fún tàbí ìdájọ́
- ☐ Ìyókù owó tí o ní
- ☐ Èyíkéyìí ìdájọ́ òfin tó parí

Jọ̀wọ́ mọ̀ wípé pípèsè àlàyé yìí kìíṣe ìfọwọ́sọ̀yà pé wàá yẹ fún ibùgbé kan. Láti gba ẹ̀dà ọ̀fẹ́ kan tí ìjábọ̀ gbèsè rẹ ṣàbẹ̀wò sí http://www.annualcreditreport.gov.

Láti ráyèsí àwọn iṣẹ́ ìrànlọ́wọ́ ìṣúná owó fún Àwọn Olùgbé New York, pe 311 tàbí ṣàbẹ̀wò sí nyc.gov/consumers.

**Ṣàbẹ̀wò sí www.nyc.gov/housingconnect láti rí ọ̀pọ̀ àlàyé tàbí bèrè lórí ayélujára.**